YORUBA



# AJO IRINAJO-AFE TI AGBAYE

## OFIN IWA TI WON FOWOSI / TEWOGBA TO DE IRINAJO –AFE KARI-AYE

AJO TO N SETO IDAGBASOKE IRINAJO-AFE NI ILE NAIJIRIA ATI ILE ISE ETO ASA ATI IRINAJO-AFE TI IJOBA APAPO NI ILU ABUJA, NAIJIRIA NI O TE E JADE

OGBUFO SI EDE YORUBA NI:
OLUFUNMILAYO AYA TAIWO
ILE EKO GIGA YUNIFASITI TI EKO
(UNIVERSITY OF LAGOS, AKOKA)

Agbekale ofin iwa to de irinajo-afe, kari-aye ti igbimo fowosi

Ipade Gbogbogbo,

A se iranti:

- pe ni odun 1997, ninu ipade ti o waye ni ilu Istanbul ni igmimo apapo ti seto idasile igmimo akanse fun kiko ofin iwa to de irinajo-afe kari-aye. Ni ojo keje osu kewa odun 1998, ni, igbimo naa pelu igmimo to n satileyin ise ilu se ipade apapo lati jiroro nipa ilana fun ofin naa.

- pe akowe fun Ajo irinajo-afe ti Agbaye pelu iranlowo amofin fun ajo naa ni o koko ko apeere ofin iwa to de irinajo-afe kari-aye. Ninu ipade oloorekoore, ogota iru re ni awon igbimo won ti fi akiyesi won han, awon ni igbimo ise ati ti agbegbe ti won se asaro lori re ni sise n tele. Igbimo apase ni o ye e wo gbeyin.

- pe ipe lo si odo gbogbo omo egbe ajo irinajo-afe ti agbaye lati ko akiyesi ati imoran ti won ko se ni akoko ipade.

A sakiyesi:

- pe ilana fun ofin iwa to de irinajo-afe kari-aye wu awon asoju ti o kopa ninu ipade keje ti igmimo to n risi idagbasoke se ni ilu New York ni osu kerin odun 1997 lori, won si ni ife si eto naa.

- pe akowe agba fun ajo yii tun jiroro pelu awon omo egbe kookan ati awon igbimo alaadani to ni i se pelu eto irinajo-afe.

- Pe ijiroro pelu awon isori wonyii, so eso rere nitori pe opo imoran ni o ti de odo akowe agba naa.

Aja naa tun teunmo o pe ero ofin iwa to de irinajo-afe kari-ate ni lati mu atunse ba awon eto ati iwe ti o ti wa latijo lori eto irina jo-afe ki o le ba akoko yii mu,ati pe ki o le awokose run awon to le fe dawole ise irinajo afe kari-aye ninu egberun odun ti a bo si yii.

Awon wonyii ni ofin iwa to de irinajo-afe kari-aye ti igbimo fowo si:

IFAARA

Ipade gbogbobgo waye ni ilu Santiago ni orile ede chile ni joj kinni osu kewaa odun 1999. Gbogbo awa omo egbe Ajo irinajo afe ti Agbaye pelu gbogbo awon asoju fun ise irinajo-afe lagbaye, asoju ipinie ati agbegbe pelu lorisirisi ni o pese.

A tenu mo ero ti a gbe kale ninu akole keta ofin Ajo irinajo-afe ti Agbaye ati pe ise kan pato ti ajo yii n se gege bi ipade gbogbogbo ti Apapo orike –ede

fowosi ni lati wa idagbasoke eto irinajo-afe ki o le je ki idagbasoke ba oro-aje, igbora-eni-ye, alaafia, oro, ati ibowo-fun enikeji lai wo eya, ede esin tabi ako-n-babo.

A ni igbagbo pe eto irinajo-afe je okunfa aiaafia, ore-s oree ati igbora-eni-ye laaarin gbogbo eda aye nipase iwa iyonda ati isooto lal si eleyameya.

Gege bi ofin Apapo orile-ede gba wole eyi ti I se eto kokanielogun ninu ipade ti won pe ni ipade Agbaye ni Rio de Janeiro ni odun 1992 pe, eto irinajo afe yoo wa fun idabobo adugbo, idagbasoke oro-aje ati igbogun ti ise patapata.

A mo pe eto irinajo ni ipa rere ati buburu lori ayika, oro-aje, adugbo tabi agbegbe niie ati leyin odi nitori idagbasoke re latijo ati ni ojo iwaju, iba a se fun afe owo, asa esin tabi fun eto ilera.

Ero wa ni lati je ki olukuluku ni eto s irinajo-afe si ibikibi ti o ba fe ni akoko isinmi won.

Sugbon, a mo daju pe ibi ti oro-aje, ise adani ati own lokan-o-jokan ba ti fese mule ni eto irinajo-afe ti le iere lori.

Lai je pe awon ilana kan ba wa eto irinajo-afe ko le ni ibase pelu awon ona okowo ati awon lie ise, nitori pe o se e se okowo ati ibasepo eda, adugbo ati idagbasoke anfani okowo okeere ati idabobo asa ati ohun afe po mo ara won.

Pelu akiyesi pe nipase ilana yii gbogbo awon igi-ieyin-ogba fun idagbasoke eto irinajo-afe iba igi-leyin-ogba, ti ipinle, ibile, ajo okowo, awon osise, ise adani, onisowo irinajo-afe, oniroyin, ati eto irinajo-afe gan an ni o ni ipa lolokan-o-jokan ti won yoo ko ninu idagbasoke eto irinajo-afe bi o tile-je pe oto ni ti tolu.

Lati mu ero yii se eto ati ise olukuluku gbodo fese mule.

Ni ibamu pelu ero Ajo irinajo-afe/Agbaye ipinnu 364 (xii) ninu ipade gbogbogbo ti o waye ni li ni ilu istanbui ni odun 1997, eyi (ero) ti I se ona lati je ki irepo ati ooto wa iaaarin gbogbo awon ti o ni se pelu irinajo-afe ni orile-ede kookan, gege bi afikun fun ikede ti o waye ni manila iori eto irinajo-afe ni adugbo ti odun 1997 ati lori iwa ase ati eto irinajo-afe ati ofin fun arinrinajo-afe ti odun 1985 ni ilu sofia labe asia ajo irinajo-afe ti agbaye.

Awon ilana ibasepo fun itupale ati imulo awon ofin wonyii ni lati wa pelu awon orisirisi akosile ti I se ohun-elo, ki awon igi-ieyin-ogba irinajo-afe le fi se awokose iwa ni opin senturi kokanlelogun.

Itumo ti a fun awon oro bii alejo, arinrinajo afe ati eto, irinajo-afe ninu ohun-elo (iwe) yii je eyi ti Apejo awon orile-ede ti o waye ni Ottawa damoran

ninu ipade to waye, ojo kerinlelogun de ojo kejidinlogun osu kefa odun 1991 ti iko to n ri si ikaniyan lapapo orile-ede aye fowo si ninu ipade ketalelogbon.

Awon akosiee wonyii ni a toka si:

- ikede Eto omo eniyan kari-aye ti ojo kewaa osu kejila odun 1848.

- Adehun laaarin awon orile-ede lori eto isuna, ohun amuluudun ati asa ti ojo kerindi-logun osu kejila odun 1996.

- Adehun laaarin awon orile-ede lori eto ilu ati iselu ti ojo kerindinlogun osu kejila 1966.

- Apejo lori irinajo-ofurufu ti weye ni Warsaw ni oje kejila osu kewaa odun 1929.

- Apejo lori isakoso oko kejila odun 1944 ni Chicago. Iru apejo bayii tun waye ni Tokyo, Hague ati Montreal.

- Apejo lori awon ohun irorun ni bode pelu ofin irinna fun ete irinajo-afe ti o waye ni ojo kerin osu keje odun 1954
- Apejo nipa idabobo asa ati ohun ajogunba ti agbaye ti o waye ni ojo kektalelogun asu kokanla odun 1972.

-ikede irinajo-afe ti agbaye ti o waye ni ojo kewae osd kewaa odun 1980. ni ilu Mnaila.

-ipinna ipade gbogbogbo elekefa ti Ajo irinajo-afe ti Agbaye ti o waye ni Ojo kerindi- logbon osu kesan-an odun 1985 ni ilu sofia ninu eyi ti won gba iwe ase ati eto pelu ofin arinrinajo wole.

-Apejo iori eto awon omo ti o waye ni ojo kerindilogon osu kinni odun 1990.

-Abajade ipade Gbogbogbo elekesan-an ti Ajo irinajo-afe ti Agbaye ti o waye ni ojo kerin osu kewaa odun 1991 nipa aabo, ipamo ati irorun arinrinajo-afe ni ilu Buenos Aires.

-Ikede lori idagbasoke ati Agbegbe ti o waye ni ojo ketala osu kefa odun 1992 ni iiu Rio.

-Adehun Gbogbogbo lori awon ise owo ti o waye ni ojo keedogun osu kerin odun 1994

-Apejo lori oniruuru Eda ti o waye ni ojo kefa osu kinni odun 1995.

-Ipinnu ipade gbogbogbo ti Ajo irinajo-afe ti Agbaye eyi ti I'se elekokanla iru re to waye ni iiu Cairo ni ojo kejilelogun osu kewaa odun 1995 iori idena eto irinajo-afe takotabo.

-Ipinnu lori iiodisi ise asewo iaaarin awon omode eyi ti o waye ni ojo kejidinlogbon osu kejo odun 1996 ni ilu stockhom.

-ipinno iori ipa ti irinajo-afe n ko ninu eto amuidudun ti o waye ni ojo kejilelogun osu karun-un odun 1997 ni ilu Manila.

## AWON ILANA OFIN

Akosile Adehun Kinni (1)

Eto irinajo-afe ti je ki igbora-eni-ye ati Owo wa iaaarin awon eniyan ati agbegbe.

1. Ipile ati abajade eto irinajo-afe gbodo je oye ati igbelaruge asa omo eniyan pelu iwa ifarada ati owo fun orisirisi igbagbo nipa ti esin, imo ati iwa. Gbogbo awon ti o ni I se pelu eto irinajo-afe ati awon arinrinajo-afe paapaa gbodo mo iyi asa ati ise gbogbo eniyan, awon eya keekeeke ati awon onile.

2. Aayan irinajo-afe gbodo wa ni ibamu pelu asa ati ise agbegbe bee owo gbodo wa fun awon ofin, ise ati asa won.

3. Eko to awon osise adugbo irinajo-afe ba ni ni yoo le ran won lowo lati gba awon arinrinajo-afe lalejo toyaya-toyaya si adugbo, to bee to awon adugbo ati awon osise ibe yoo fi le ba arinrinajo aye ni bee ati awon ti o fe ati eyi ti o n reti lati odo awon ara adugbo.
4. Tse awon alase ilu ni lati mojuto aabo awon arinrinajo-afe ati ohun ini won. Eto pataki/pato gbodo wa fun iroyin, idora eto ma-da-n-dofo ati iranlowo loorekoore fun awon ajeji arinrinajo-afe.

Ijiya to to labe ofin gbodo wa fun eni ti o ba hu iwa palapala bi I jijjgbo, ija dideruba arinrinajo-afe ati gbogbo osise nipa irinajo-afe biba ohun elo eto irinajo-afe ati ohun isenbaye adugbo je.

5. Awon arirnrinajo-afe ko gbodo huwa ti o lodi si ofin ilu, agbegbe tabi orile-ede to won lo.Awon iwa bi I gbigbe oogun oloro, ohun-ija,tabi awon ohun ti o lewu fun ara Ilu wole ko gbodo sele.

6. ki awon arinrinajo-afe to o bo sona lati lo si Ilu miiran fun irinajo-afe won gbogbo ti se iwadiinipa aabo eto ilera ati awon ewu ti o wa ni ilu naa eyi yoo je ki o le mura daadaa fun ohunkohun ti o ba ba pade lohun-un.

Akosile Adehun keji (2)
<u>Eto irinajo-afe ni okunfa aseyori fun eda kookan ati gbogbo eniyan lapapo.</u>

1. Eto ati ise irinajo-afe ti a ka si isunni ati idera, ere Idaraya ati ona si asa gbodo je ona aseyori fun eni kookan ati gbogbo eniyan iapapo. O tun je ekunfa eko, ifarada ati ona lati mo orisirisi iyato wa iaaarin awon eniyan ati asa won ierisirisi.

2. Awon eto irinajo-afe nilati bowo fun ekunrin ati obinrin niteri pe dogba-n-degba ni won won gbodo gbe eto omo eniyan laruge paapaa awon ipin to gbelege awon bi I omode, arugbo, abirun, eya kekeeke ati awon omo onile.

3. Gbogbo lwa ti ko ba wa ni ibamu pelu ete ati ero irinajo-afe awon ire-omonikeji-je ni o gbodo ri idinu ofin liu ti arinrinajo ti wa ati ofin llu ti o ti dese naa.
4. o ye ki a gbaruku ti irinajo-afe ti o je mo mimo esin, eto ilera, eto eko ati asa tabi ede awon eya miiran iru awon eya miiran, iru awon irinajo-afe bayii iere.
5. o ye ki anfani irinajo-afe ere re nipa ti owo, ohun amuluudun ati asa pelu awon ewu re wa ninu eto ekoile iwe

Akosile Adehun keta (3)

<u>Eto irinajo-afe je okunfa idagbasoke to fese mule</u>

1. gbogbo awon to ni I se pelu idagbasoke irinajo-afe gbodo ni I ikokan lati ri I pe eto irinajo-afe je ona idagbasoke oro-aje fun anfani awon iran wonyi ati iran ti n bo lojo iwaju nipa didabobo awon ohun adayeba gbogbo.
2. Awon alase ti orile-ede, ti ipinle ati ti ibile ni lati je ki awon eelo irinajo-afe bi I omi, ohun imu-sagbara pelu eto lati dena ifi-ohun sofo, je won logun ninu eto ijoba won.
3. Akok o isinmi lenu ise fun awon osise olowo-osu ati ti awon akekoo ko gbodo bo si akoko kan naa. Ki aye ati igbadun ba ie wa fun arinrinjo-afe ati awon to n seto re.
4. Awon ohun-elo eto irinajo-afe ati akitiyan re gbodo wa ni ibamu pelu ona lati daabobo awon ohun ajogunba ti o ni I se peiu awon ohun elemii ninu igbo ati orisirisi eniyan ni ori ile. Awon osise ati awon to n ri si idagbasoke eto irinajo-afe ni lati sora pelu ifura nigbakuugba ti ise won ba je mo asale oke giga, inu igbo, eti okun ibamu pelu egba gbogbo.
5. Eto irinajo-afe ti o da lori awon ohun isenbaye ati nipa eniyan ti o si fun awon ohun ajogunba ati awon eniyan agbegbe naa ni owo yoo lere gidi.

Akosile Adehun kerin (4)

<u>Eto irinajo-afe n se amulo asa ajogungba omo eniyan, o si n gbaruku ti idagbasoke re</u>

1. Bi o tile jepe gbogbo ohun elo irinajo-afe je ajogungba gbogbo eda, awon eniyan agbegbe ti okookan ni eto ati ase lori won.

2. Gbogbo eto ati akitiyan iriajo-afe gbodo je ni towotowo fun awon ise ona ohun isenbaye ati ajogunba pelu ipamo fun iran ti n bo lojo iwaju. O ye ki awon ohun isenbaye ati awon ile isin ti o je ti aladani le irinajo-afe won. Owo gbodo wa fun awon oninnkan lai si etanu.

3. A gbodo maa lo die ninu awon owotia ba n pa ninu irinaje-afe siawon ohun asa ati isenbaye, lati fi tun awon nnkan naa se idagbasoke ati idabobo won.

4. A gbodo seto awon akitiyan eto irinajo-afe ni ona ti imulo ati idagbasoke yoo wa fun awon ise owo ati ere-idaraya ti ibile kookan dipo ki won di oloogbe.

Akosile Adehun Karun-un (5)

Eto irinajo-afe je akitiyan to sanfani fun awon orile-ede ati agbegbe te gba alejo.

1. Gbogbo awon agbegbe ti o kopa ninu ete irinajo-afe ni won ni lati pin ninu ere ti ba jeyo paa paa nipa nipa pipese ise fun awon ara agbegbe naa.

2. Gbogbo akitiyan eto irinajo-afe gbodo je eyi ti yoo mu igbese-aye awon ara ilu bee dara si I . A gbodo fun awon ara agbegbe irinajo-afe ni anfani lati kopa ninu gbogbo ise ti o ba ni I se pelu eto irinajo-afe adugba won ki won si ri owo gba.

3. A gbodo se akiyesi pataki si awon isoro ti o wa ni awon adugbo ti o soro die lati se eto irinajo-afe awon adugba bi I asale, oke giga ati okun.

4. Gbogbo awon esise ati onigbowo eto irinajo-afe ni o gbodo mo ipa ati onigbowo won n ni ninu agbegbe ati ayika naa. O ye ki awon eniyan awon ero ati agbegbe naa ati awon esise naa jo jiroro nipa eto, ero ati abajade awon idawole won fun ojo iwaju.

Akosile Adehun Kefa (6)

<u>Ojuse awon onigbowo idagbasoke eto irinajo-afe.</u>

1. O je ojuse awon eto irinajo-afe lati je ki awon arinranjo-afe mo ohun gbogbo nipa ilu ti won n lo, Orisi ohun irinna ti o wa, akoko ati orisirisi irorun ti arinrinajo-afe ni lati reti. O ye ki osise yii je ki arinrinajo-afe mo nipa gbogbo eto adehun, iye owo, ati iru itoju ti yoo wa ni akoko irinnajo-afe naa. Agboye gbodo we laaarin awon mejeeji paapaa nipa owo-itenran ti o ye ni sisan bi enikeni ba ye adehun.

2. Awon osise irinajo-afe gbodo ni asepo pelu awon alase agbegbe won lati ri I wi pe eto aabo, ipamo, ilera, ounje ati idena ijamba, ati eto maadandofo wa fun awon arinrinajo-afe ni ikawo won. Ojuse won gbodo wa ni ibamu pelu Ilana ti ijoba orile-ede la sile. Ti awon osise ba se adehun won gbodo san owo itanran fun awon arinrinajo-afe.

3. Osise gbodo fi aye sile fun arinrinajo lati sin esin re ni akoko ti o ba wa lodo re. Ki o si tun mo nipa asa ati ise isin re si I

4. Ti ajo to n seto irinajo-afe ba je gbese ti irinajo bee ko ba waye mo ajo naa, egbe won, awon alase orile-ede arinrinajo ati orile-ede tGba alajo ni lati seto lati da arinriajom naa pada si orile-ede re.

5. Ni akoko rogbodiyan, eto ati ise ijoba orile-ede ni lati je ki awon omo orile-ede re mo awon ibi ti won le rin irinajo-afe si, paapaa ilu oyinbo laisi ewu. Awon ikilo wonyii peu imoran oludamoran nipa irinajo gbodo di mimo fun gbogbogbo. Nigba ti alaafia ba pada si orile-ede ni awon imoran pari ise.

6. Awon oniroyin paapaa awon ti n rin irinajo pelu awon ile ise ibanisoro gbodo maa so ati ko iroyin tooto jade paapaa ni akoko ti rogbodiyan ba wa. Iroyin pipe ati ti otito ti won ba n fun ara ilu ni yoo dari awon osise irinajo-afe ati awon arinrinajo-afe bakan naa. Orisirisi awon ero iba-ni-soro ti ode-oni ni won le lo. Won ko gbodo polongo irinajo-afee tako-tabo.

Akosile Adehun keje (7)

Eto awon eniyan si irinajo-afe.

1. Ko gbodo si idena fun eda alaye kankan nipase irinajo-afe lati wadi ati gbadun gbogbo ohun rere ti

Oluwa da si aye. Okan ninu won ona ti o dara lati lo akoko isinmi ni rinrin irinajo-afe laaarin orile-ede abinibi ati okeere.

Eto eda si irinajo-afe ni o dabi eto si oorun ati faaji pelu iwonba akoko ise pelu isinmi to lowo lori. Eto yii ni, ikede eto omo eniyan kari aye ipin kerinlelogun, ati adehun laarin awon orile-ede lori eto si Isuna, Ohun amuludun ati asa, Akosile keje ipin D jerii si.

2. Awon alase ilu ni lati gbaruku ti idagbasoke eeto irinajo-afe paapaa ti elegbejegbe eye ti o sokunfa anfani si irinajo, isinmi ati faaji.

3. Awon alase ilu ni lati gbaraku ti ada adagbasoke eto irinajo-afe paapaa ti elegbejegbe eyi ti o sokunfa anfani si irinajo, isinmi ati faaji.

4. Awon alase tun gbodo gbaruku ti irinajo-afe laarin awon odo, akekoo, ebi, agbalagba ati awon abirun.

Akosile Adehun Kejo (8)

<u>Ominira ti egbe Arinrinajo-afe ni.</u>

1. Awon arinrinajo-afe ati awon alejo ni anfani lati gbera lati ibi kan si ekeji ni aarin orile-ede asa won tabi ni okeere, pelu ibewo si awon ibudo ni ibamu pelu ofin orile-ede gbogbo laisi eto-pinpin tabi eleyameya gege bi o ti wa ninu ikede eto omo eniyan kari-aye, akosile ketala.

2. Awon arinrinajo-afe ati alejo gbodo ni eto si iba-ni-soro nile tabi leyin odi, eto ilera, eto ofin,

Won gbodo le de odo asoju orile-ede won ni ibamu pelu ilana ti a wa ni orile-ede ti won ti je alej

3. Gbogbo asiri ati alaye nipa igbesi aye arinrin ajo-afe ati alejo kookan ni ko gbodo ti sita. Ako gbodo fi awon asiri ti a gba sinu ero tafala rara.

4. Adehun gbodo wa laarin gbogbo orile-ede lati so gbogbo isoro orinkinnwin bii gbigba iwe irinna, iwe ilera, ase bode lati rin irinajo wo orile-ede kan ku. Gbogbo awon ofin-irinna gbogbo wa ni iwon-tun-wonsi ki o le rorun fun awon eniyan lati rin irinajo lo si ilu tabi orile ede ti won ba fe. Inira fun awon onigowo eto irinajo afe gbode dinku.

5. Arinrinajo gbodo le gba awon owo-ina diedie fun irinajo won, ni igbamu pelu eto oro-aje orile –ede ti won ti n bo.

Akosile Adehun Kesan-an (9)

<u>Eto awon osise ati onisowo irinajo-afe</u>

1. O ye ki awon alaakoso eto irinajo-afe nile ati leyin edi, mojuto sisan owo osu –ise awon osise eto irinajo-afe ibaase ti ijoba tabi ti alaadani gege bi eto won paapaa nigba ti a ba wo bi ise won se lewu ati soro si.
2. O ye ki eto eko wa fun osise irinajo-afe ki o to bere ise ati loorekoore. Eto won ni lati ni aabo to daju nibi ise, ewu lenu ise gbodo dinku. Awon osise to ti pe lenu ise ni eto si orisirisi iwuri.
3. Enikeni ti o ba ti je alakikanju ti o si ni oye ati ife lati se ise irinajo-afe ni o ye ki o gba eko labe ofin ki o si ri atileyin lati da ile ise irinajo-afe sile lai si wahala tabi iyonu lati odo awon alakoso ijoba.
4. Ogbooro iriri nile ati leyin odi ti awon oga ati osise eto irinajo-afe n ni ni akoko irinajo won ni o n je ki ise naa tubo maa gberu. Oye ki iru anfanii bayii wa fun ggogbo osise ni ibamu pelu ofin orile-ede ati ipinu awon orile-ede okeere.

5. Awon orile-ede okeere ti n kopa ninu eto irinajo afe ko gbodo di eegun eja ha awon orile-ede ti o gba won lalejo lorun. Won gbodo lowo si eto idagbagba soke adugbo nipa lilo ninu ere awon fun adugbo dipo ki gbogbo re maa koja si orile–ede ti won ati wa. Won ko gbodo si aye ti won fun ni orile ede ajeji lati sowo irinajo-afe lo. Aye yir je okun fa asepo fun idagbasoke eto pasipaaro oro aje laarin awon orile-ede.

6. Ibasepo to fese mule laarin awon orile-ede to n sowo irinajo-afe ati orile-ede to n gba a, ni yoo le je ki idagbasoke wa fun eto irinajo-afe. A gbodo pin ere idagbasoke yii ni ori-o-jori.

7. A ro gbogbo omoegbe Ajo irinajo-afe ti Agbaye lati polongo awon ofin iwa wonyii laarin awon onigbowo eto irinajo-afe, ki awon naa si tanan kaa.

8. Akowe agba fun Ajo irinabo-afe ti agbaye ni lati je ki olu-ile-ise Apapo orile ede mo nipa awon ofin wonyii, ki won gba a ki won si fowo si I gege bi ara igbese mimu imoran lo.

Akosile Adehun Kewaa (10)

<u>Lilo awon ilana ofin iwa fun eto irinajo-afe ti agbaye</u>.

1. Awon onigbowo eto irinajo-afe ni ti ijoba ati ti aladani gbodo sowopo ninu lile awon ilana ofin wonyii, ki won si ri I pe won daadaa.

2. Awon onigbowo eto irinajo-afe gbodo bu ola fun eni ti ola to si nipa mimo iyi iranlowo ti orisirisi eka n se fun idagbasoke eto irinajo-afe. Akoko iru eka bayii ni Ajo irinajo-afe ti Agbaye, awon aja alaadani to mo nipa ipelongo ati idagbasoke irinajo-afe, ajo to n ri si

idabobo eto omo eniyan, aje to n si ilera agbebe, pelu ibowo fun iliana ofun orile-ede.

3. Ti ede-aiyede ba wa leri lilo awon ofin iwa fun eto irinajo-afe kari aye, awon onigbowo eto yii gbodo kan si igbimo ti a pe ni igbimo agbaye lori iwa eto irinajo-afe.

4. Ki gbogbo awon onigbowo idagbasoke eto irinajo-afe ti orile-ede, ipinle,ibile, onisowo egbe onisowo, osise, ajo irinajo-afe, adugbo to gba alejo ati arinrinajo, huwa ni ibamu pelu ofin irinajo-afe ti it o wa yii.

5. Eto lile awon ilana ofin wonyi yoo wa ni ibamu pelu itosona igbimo Agbaye lori iwa ati eto irinajo-afe, eyi ti ipade gbogbogbo gba wole nipase igbimo alase ti Ajo Eto irinajo-afe ti Agbaye.

6. A damoran pe:

   (a) Ki gbogbo momo egbe ati ki I se omo egba Ajo Eto irinajo-afe ti agbaye mu ilana ofin ajo yii lo ninu ofin orile-ede won, ki won si fi to igbimo leti.